IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ *ORE AIYE TENI* GBOGBO LAWA

No 1,580 WEDNESDAY DECEMBER 8, 1965 (2D)

Mọto Ayọkẹlẹ Pa Ọmọ Kan

EBUTE—MẸTTA:— Jinnijinni dabo gbogbo awọn enia ti nwọn wa ni tosi nigbati mọto ayọkẹlẹ kan No. LK 9021 kọlu Ọdọmọdebinrin kan, Beatrice Adekunle, ti o ngbe nọmba 515, Patey Street, Ebute – Mẹtta, ọmọ na ti ṣe fẹ sare kọja oju titi ni Opopo Herbert Maculay, ti ọmọ na si jku bamubamu ni kutukutu owurọ ana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi.

Irohin awọn Ọlọpa Ebute – Mẹtta fi ye wa ni ọsan ana wipe, ọmọ na fẹ sare kọja oju ọna ni deede agogo mẹfa abọ owurọ ọjọ na ni o ba sare pade agbako ni ọjọ na nigbati gbogbo awọn oṣiṣẹ ti bẹrẹsi maa lọ si ibi iṣẹ wọn ni owurọ ọjọ na.

Lẹsẹkẹsẹ ti ijamba na ti ṣẹlẹ ni gbogbo awọn enia ti nwọn nlọ si ibi iṣẹ wọn ati gbogbo aladugbo ti, nwọn ni tosi ibi ti ijamba na gbe ti ṣẹlẹ ti sare de ti nwọn si wa ṣe ajọ ọmọ na, ṣugbọn bi awọn enia ti ṣe to, ni owurọ ọjọ na ni ọmọ na ku bamubamu.

Lojukanna ni awọn enia ti nwọn wa ni tosi ibẹ ti sare lọ ranṣẹ si awọn Ọlọpa ni Teṣan ni Ebute-Mẹtta wipe ki nwọn tete maa bọ lati wa wo ohunti o ṣẹlẹ.

WO OJU EWE KẸFA

ILE IGBIMỌ ASOFIN IJỌBA IWỌ ORUN FẸ ṢE IPADE

IBADAN:— Ni deede agogo mẹrin irọlẹ ana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni Irohin kan de si ile iṣẹ wa lati ọdọ Oniwe Irohin wa ni Ibadan fi irohin kan ranṣẹ si wa lati inu ile iṣẹ wa ni Ibadan wipe, Ile Igbimọ Asofin Ijọba Iwọ Orun Naijiria ati Ile Igbimọ Aṣofin awọn Ọba yio ṣe ipade wọn ni owurọ ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi.

Irohin na tun ṣe alaye siwaju pe ni deede agogo mẹwa owurọ ọjọ na ni nwọn yio ṣe ipade na, ati pe awọn ile Igbimọ aṣofin Ijọba ati ti ile Igbimọ awọn Lọbalọba ni nwọn yio jijọ ṣe ipade na ni aṣepapọ ni ọjọ na.

Siwaju sii, irohin na tun fi ṣe afikun ninu ọrọ rẹ pe ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi, Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni o ṣe ikede bẹ ẹ ni Ibadan ni owurọ ana wipe awọn ile Igbimọ mejeji na yio ṣe ipade ni ọjọ na.

Irohin kan eyiti a tun ri gba lati ile Iṣẹ Minista Alamojuto eto Irohin fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni ana kan na, irohin tun fi ye wa wipe, lati ile iṣẹ Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni ikede na ti jade lo de ile iṣẹ wọn ni ana.

Alhaji Dauda Adegbenro

Adele Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

A gbọ wipe Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi ni o pe Ipade Ile Igbimọ na, o si ṣe alaye ninu iwe ti o jade ni ana na wipe, on(Gomina) na pe ipade na ni abẹ Ofin eto iṣelu Orilẹ ede Naijiria Ori ọgbọn gẹgẹbi aṣẹ ti nwọn fun on ti abẹ ofin na ni Ipinlẹ Iwọ Orun

Irohin na tun ṣe alaye wipe akọwe Ile Igbimọ na Ọgbẹni Akintọla ti bẹrẹsi kọwe si gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na lati ana wipe ki nwọn ma ṣe alaiko wa si ipade ti nwọn fẹ ṣe ni ọjọ na pẹlu.

A tun gbọ pẹlu wipe akọwe Ile Igbimọ na ti tun kọwe si gbogbo awọn Ọba ati Ijoye ti nwon jẹ ọmọ Ile Igbimọ na pẹlu wipe ki awọn na maṣe alaiko wa si ipade ti nwọn fẹ ṣe ni ọjọ na, ki wọn si wa pẹlu.

Onirohin wa kan fi ye wa ni ana pe ipade ti nwọn yio ṣe ni ọjọ kẹsan oṣu yi ni yio jẹ ipade kini ti awọn ọmọ ile Igbimọ na yio kọkọ ṣe lati igbati nwọn ti dibo tabi ti nwọn ti yan awọn enia na gẹgẹbi Aṣoju Ipinlẹ Iwọ Orun sinu ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Onirohin wa kan tun ran wa leti pe ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi ni nwọn dibo yika gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati yan awọn Aṣoju titun si inu ile Igbimọ na.

Ṣugbọn lẹhin ibo na tabi lati igbati awọn enia na ti dibo tan ni rudurudu ati rogbodiyan ti bẹrẹsi ṣẹlẹ yika gbogbo Ipinlẹ na ti awọn enia na si ndana sun ile ati mọto awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan yika gbogbo Ipinlẹ na.

Nigbati nwọn di ibo na ti o di ọjọ keji ni Alhaji D. S. Adegbenro Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre kọwe si Ọlọla Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi wipe, ẹgbẹ on lo wọle ninu ibo ti nwọn di ni Ipinlẹ na, on si fẹ ri Gomina na ki on si le ṣe eto lati yan awọn ti nwọn yio jẹ Minista fun on ni Ipinlẹ na ..ti ninu Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ṣugbọn ni ọjọ keje ti Alhaji Adegbenro ṣe ifilọ wipe awọn enia mẹtala ni nwọn yio jẹ Minista fun on ninu Ile Igbimọ na ti o si tun da orukọ nwọn ni awọn Ọlọpa ba lọ mu Alhaji Adegbenro ati diẹ ninu awọn ọmọ ẹhin rẹ.

Oloye S. L. Akintola

Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

Awọn Ọlọpa ṣe alaye wipe, Ọlọla Fadahunsi ti

WO OJU EWE KẸFA

AṢEJU BABA AṢETẸ

LATI ỌWỌ
A. Akanni

Ni Igba Iwasẹ Ọkunrin kan nbẹ Ọkunrin na jẹ ẹda ti Ọlọrun tete gbega nipa owo eyi mu ki o ni ọpọlọpọ iyawo ati ọmọ awọn ọmọ iransẹ koniye bi ọla ọkunrin yi ti pọ to on pẹlu ọba ilu lo njọ ji roro lori ọrọ ilu ṣugbọn ni igbati igba yi pada owo tan ọla rẹ lọ silẹ eyi to wipe aburo rẹ ti Ọlọrun tun se lolowo lo tun nfun ni onjẹ on ati awọn ọmọ rẹ adura mi si bi ti mo sọrọ de yi ni wipe

Ki Oluwa ko ma se dawa pada sehin kama se jiya kẹhin ọrọ

A ni nigbati awọn iyawo ti ri pe ko tun si tata loju Yan Yan mọ loni kaluku ti fẹsẹ ehin dele wọn ju ogbo ni silẹ lailai ko gbere.

Ni ọjọ kan okuurin yi ro ọrọ rẹ titi de bi pe ki onku ku ku ọ sa fun on ti mbọ - ọpọlọpọ enia on tun pada di ẹniti aburo on tun bọ yi ọkunrin yi ro ọrọ de bi wipe Iku to le yi ku fun on ni wipe ki on lakaka lọ bẹ si inu odo lọsọ ti ọkunrin yi ti pinnu lati lọ ku o mura o de ti odo ma kan to wa ni eti ilu nwọn

Nigbati o de bẹ o ba asọ ti o wọ sile o lọ ori apata nla kan ti o wa l rin odo na o kọ ẹhin sodo o fẹ bẹ sinu rẹ Ṣugbọn bi o ti bọ sodo ni alijannu to wa lo do ba gbe pada soke eyi ya lẹnu pupọ lati nn ba ara rẹ ni ọwọ osi ọwọ ko ko ri ẹni to gbe soke rara otun bẹ sodo lẹkeji Alijannu na tun gbe soke Ni gbati o pe ẹlẹkẹta ti o tun bẹ sodo ti Alijannu tun gbe soke Alijanna na duro ti oju t Ọkunrin yi ni ki on yi pada pe ki nrẹ kini oju on pẹlu Alijannu se Alijannu bere lọwọ re pe kini ohun ti o ndun e lọkan to bẹ ti o mu ẹ fẹ ku sodo.

Ọkunrin yi ko gbogbo ẹdun ọkan rẹ fo sọ Alijannu sọ fun un pe ki o ma ṣe ku rara pe eyi ko to on to le bina ka si, Alijannu fun ni oruka oje kan o ni ko fi sọwọ ti o ba pada de ile gbogbo nkan ti o ba ro lọkan rẹ wipe lo mama ri Ọkunrin yi gba oruka na o dupẹ lọwọ Alij nuu ki o to yi pada mọ lọ ni Alijannu o ba kilọ fun ọkunrin yi wipe, lilọ ni onlọ yi nko fẹ ki o fi oruka yi ṣe aseju o Ọkunrin yi ni rara o on ko ni fi ṣe aṣeju rara, Ọkunrin yi pada si ile ki o to de ile iyawo aburo rẹ ti gbe onjẹ rẹ ka ori teburu onjẹ rẹ fun bi o ti wọ ile o jako o si onjẹ ti wọn de mọlẹ, o ri wipe, ẹran kan lo wa ninu ọbẹ na, o de pada, o fi ọwọ lori onjẹ na o ro lọ kan ararẹ wipe nbari ki ẹki ri ẹran kan to wa ninu ọbẹ ko di ekiri ẹja mẹrin lẹsẹkẹ sẹ ekiri ẹran na ti di ẹkiri ẹran mẹrin lotitọ ni igba ti o si wo o ba ẹja mẹrin nito to inu rẹ dun o bẹrẹ si jẹun nigbati o jẹun tan to ri wipe ọrọ Alijannu ṣẹ ko sọ nkankan fun awọn ọmọ ati aburo rẹ atiko onjẹ alẹ to ki iyawo aburo to gbe onjẹ wa ọkunrin y ti ro lọkan ararẹ wipe iresi ati ẹja ti nwon fi ouoro se lo nwu onje, ki o to ro lọ kan tan iwaju re ni o ba elu awo meji ti eja wa ni nu okan ati iresi ninu okan o nwo, o de mọie niwaju re nigbati iyawo aburo re de ti o gbe onje ale wa ti o ri awo olomori meji ti wọn de mọlẹ niwaju rẹ eyi ya lẹnu pupọ ṣọgbọn ko le be re ibiti iyẹn ti wa ero ọkan rẹ ni wipe boya awọn iyawo ti o nfẹ lo gbe wa ni nigbati iyawo aburo lọ tan ọkunrin yi bẹrẹsi ma jẹ irẹsi rẹ ko fi ọwọ kan onjẹ ti iyawo aburo rẹ gbe wa de bi ti yio si wo.

Ni ọjọ keji jiji ti ọkunrin yi ji to wo aṣisa ẹwu to wọ otun ro lọkan pe nba ri kọ

Akisa aṣun mi yi di ẹwu tuntun ki o to sọbẹ tan ẹwu na ti di tuntun ọkunrin yi ri apoti o fi fo kan o gbe apoti o fi fo na ṣodo oro wi pe nbari ki orisirisi ẹwu agbada Sokoto tila kun inu rẹ bi oti ro tan sisi ti yio si as atata nlo kun inu rẹ ọkunrin yi tun gbe apoti ti o ti ni o owo si tẹlẹ wa oro ni ọkan rẹ wipe nbari ki owo kun inu apoti mi yi we re apoti kun fun owa ki a mase fa gun lo titi gbogbo nkan ti ọkunrin yi ba sunro lọkan ni nri be fun ṣugbon ọkunrin yi ko so idi abajọ ọrọ yi fun Aburo rẹ rara eyi jẹ iyalẹnu nla fun aburo rẹ yi pupọ aburo yi fi inu fun le titi ko ti idi ọrọ yi rara Ọkunrin yi bẹrẹ si na owo bi ẹl da onra on ohun to wu bi alejo ka bawa ki ọkunrin yi bi oti uro l k n n onri fun bi o ba ti wipe ki iyo Bia m fa a

Ni igara bi oba ti nwo inu yara beni yio ko jade

WO OJU EWE KARUN

Ọlọla Branko Ṣe Alejo

Ni opin ọsẹ ti o koja lo yi ni ọlọla Dọkita Branko Karapandza, Asoju Ijoba orilẹ ede Yugslavia ni Naijiria ṣe abẹwo abuyjkun ati ẹyaye rarpẹ kan si ile iṣẹ Minista Alamojuto eto owo fun Apapọ Ijọba Naijiria ti awọn mejeji jijọ fikunlokun. Onirohin wa ti o lọ sibiti awọn eniamejeji gbe ta ọrọ wọn sọrọ ra ṣe alaye wipe ni deede agogo mẹwa owurọ ni Asoju Ijọba na de ile iṣẹ Minista na ti awọn mejeji si ki ara wọn tayọtayọ.

Dokita Mbadiwe ati Dọkita Branko

Onirohin wa kan ran wa leti wipe Dọkita Branko ti se ileri ni opin ọsẹ ti o koja lo yi wipe Ijọba on yio pese adoje ọkẹ pọnun £3,600,000 fun orilẹ ede Naijiria fun iṣẹ Idagbaṣoke ati ilọwaju iṣẹ Aje.

O si tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ pẹlu wipe on fẹ ki Minista eto Ile wiwọn ati ile gbigbe wa ṣe abẹwo orilẹ ede Yugoslovkia ki awọn na le ba mọ iru ile ti o ye fun awọn oṣiṣẹ lati kọ fun wọn nigbati Ijọba ba ma kọ ile fun awọn oṣiṣẹ.

Nigbati Minista na yio fi kuro ni ọdọ Dọkita Mbadiwe, o fun Dọkita Mbadiwe ni iwe kan ti ma fi ṣe iranti ọjọ ati asiko ti on ṣe abẹwo wa sọdọ rẹ.

Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

Ilu Odogbolu Nfe Ile Iwosan Nla

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe ryin to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ṣe iranlowo yi fun awa enia ilu Odogbolu ni ekun Ijẹbu lati tete kọ ile iwosan nla fun awa enia ilu na ati pe o ti to ọdun diẹ bayi to je wipe a ti nkesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ṣe iranlọwọ yi fun wa.

Ọpọlọpọ enia lo jẹ wipe yio fi ara gbogbo tabi pe ki aisan kọlu eyiti o jẹ pe ti nwọn ko ba ti pe awọn enia lo si Ile Iwosan ti ilu Ijẹbu Ode tabi Shagamu eyiti o je pe ki nwọn to de ile iwosan ni awọn enia na yio ku lori pe aisan na ti wọ wọn lara pupọ ju.

Inu awa enia ilu Odogbolu yio dun bi Ijọbu Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria ba le ṣe iranlọwọ yi fun wa ki nwọn ṣe awọn nkan miran eyiti yio mu ilọsiwa ju ba ilu wa.

Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o

Emi ni
John Adebayọ
Ijẹbu-Odogbolu

Balewa o Di Owo Rẹ

Kosi ẹni ti yio ri bi Ipinlẹ iwọ orun ti wa ni asiko yi ti inu rẹ yio si bi gbogbe rẹ ti nlọ ṣegeṣege ti ko si ofin mọ rara ti ẹmi ọmọ enia ko jo wọn loju mọ ti wọn npa ara wọn bi ẹni pa ẹja ninu odo ti olukaluku si nṣe eyiti o tọ loju rẹ bi o ba ofin o ko ba ofin mu o nwọn ko fẹ mọ

Bẹni eyiti nwọn ṣe ninu ile igbimọ Asofin ni Ibadan to eyi ti ọla la Balewa fi se ofin pajawiri ni Ipinlẹ na.

Mo fẹ mọ idi rẹ ti ko fi le si ofin pajawiri ni asiko yi nigbati ẹmi, ile dukia nṣofo ni oiojumọ kakakiẹ kọ ibi ara si ọrọ ti ilẹ Naijiria paapa Ipinlẹ Iwọ orun eyi ko kan nyin lọwọ ati ẹsẹ ni ẹ nranju si

Nitori na ki ọrọ yi ki o mas batu burujo bayi lọ mo bẹ ẹnyin ti ẹ nwa ire ọmọ odua ki ẹ ma jẹki ọrọ yi baiẹ loju nyin o

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi Olotu

Emi ni
L. Ogunyẹmi

ILESHA

Kere o Kere o! Akiyesi Pataki

Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanuu Egbogi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na niẹwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imoran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti ami di tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun ngbakugba ara wiwo, Ẹsanri ẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko di ro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki ṣiak ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe enia nipa sise di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla si'e mefa abọ (6/-6 pere Igo kekere ṣile mẹta abo (3/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone:- 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

GBANJO!

NOVEMBER 15th — DECEMBER 15th 1965

Iwe itumo Ala, Etutu Sise ise wiwo, Ojo ibi Omo, ati Ogun Ajebidan 3s6d di 1s6d

Iwe Afose Isedale Yoruba ati Psalmu Ajebidan, 3s 6d di 2s

Turari 2s 6d Paketi di 1/-

A le ri iwe wonyi ra lodo :-

J. O. SHOYINKA P. O. Box 159 Mushin. SHOYINKA ni 9, Iyalla Street, Mushin.

Awon Soja Fi Iya jẹ Onitasi

SURULERE: Aanu abiyamọ ṣe awọn enia ti o ngbe agbegbe Ataọ ni Surulere ni ojọ Ẹti tiṣe ọjọ kẹta oṣu yi nigbati awọn Sọja gbe m to nwọn ti nọmba rẹ jẹ NA 2253 lati Barẹke ti nwọn ngbe agbara ti nwọn ara n nw n ba ṣe pẹ i mọto takisi kan ti nọmba rẹ jẹ LB 2823 Lọgan awọn Sọja yi ti sọ kalẹ n wọn si lọ ba awọn onitakisi na ti nwọn bẹrẹsi ni lu

Nigbati awọn Sọja bẹrẹsi na awọn enia to wa ninu takisi pẹlu ẹniti o nwa mọto na ni ina kuna ti ẹjẹ si nyọ loju lori leti ati ni gbogbo ara awọn ti nwọn si nyi ninu agbara ẹjẹ sibẹ-sibẹ awọn Sọja yi ko dẹhin lati na wọn ti o wu wọn.

Bi awọn ti nwo bira ti awọn Sọja yi ngna si awọn ẹnikẹni lara ti ri jẹ ti njade lara awọn enia to ninu takisi na ni gbogbo wọn bi ya wọ iyara nwọn lọ ti nwọn si ti ilẹkun mọ ri, ti elomiran si fi ẹsẹ fẹẹ pẹ, ọrọ buruku koni ṣe oju awọn,

Awọn Sọja yi ko da ọwọ duro ti,i, ti awọn Ọlọpa ti ntọju oju ọna fi de ti nwọn si bere lọwọ wọn pe, iru ẹṣẹ wo ni awọn eleyi ṣe o ti e fi nfi iya jẹ wọn to bayi?

Nigbati nwọn ko le fun awọn ọlọpa na ni esi ti o jagere ti nwọn ba ko awọn Sọja lọ si teṣan awọn Ọlọpa lati lọ wadi ọrọ lẹnu wọn,

Awọn ọlọpa si ti ko awọn enia ti o wa ninu takisi na pẹlu ẹniti o nwa lọ si ile ogun fun itọju.

YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 – Feb 20) Iṣẹ yio pọ niwaju rẹ lati ṣe loni, nitorina ki o tun ara rẹ ṣe giri, iba aye ti o ba ri fun ta ji ki o lo o lọdọ awọn ọrẹ rẹ, ohun kan ti o si nṣe lọwọ yio ni ilọsiwaju.

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Ṣọra ki aarẹ maṣe mu ọ loni, ire si mbẹ fun ọ lọnakọna, ki o si ma e yọya si gbogbo enia ki inu rẹ si ma dun si gbogbo enia.

ARIES (Mar – April 20) ṣe i ki o ṣe ara giri ki o ba le ri aye lati yanju awọn iṣoro ti o wa fun ọ, I u rẹ y o dun loni tobẹ ti iwọ yio fi gbagbe ohun ti o ndun ọ.

TARUS (April 21 May 20) Ri o ṣọta y'ya enia ni owo rẹp.t loni ṣe jẹjẹ ki o si ṣe suru ọpọlọpọ ire ni yio si sile niwaju re.

GEMINI (May 21 June 21) Irawọ rẹ yio ni alatako loni ṣe suru ki o s dakẹ jẹjẹ ọpọlọpo awọn ohun ti o ti ngba bi er yio jade si otito.

CANCER (June 22 Julo 22) Gbo ikilo yi maṣe jade lo si ode ni alẹ oni bẹni kio maṣe pẹ ki o to wọle lo d a-bulẹ ṣe gbogbo ukan iwontunwons loni ki o ma ṣe fi iṣẹ pa ara rẹ lori.

LEO (July 24 Aug 22) Aye yio gba o ni bi kibi loni, ire lwaju ti o mbo ni ki o ma wo.

VIRGO Aug 23 Sept 23) Igba le yi pada tobẹ ti o fi jẹ pe gbogbo ohun ti o ngba lero ni iwo yio yi pada ti iwo yio si mu o a m ran pọn.

LIBRA Sept 24 Oct 23) Ọr kekere tiko to oro kan le ko arẹ okan wa tu o ṣe suru.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Bio ba di asilẹ ki o ṣe jẹje ati p l ẹ ẹ maṣe jẹki oro oro o dasi ki o ma ba di oro s l r un

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Ọpọlọpọ oro ni yio dele lori ti iwo y o ni lati da si inu rẹ ṣugbọn oro ti nwo yio n e iowo rẹ yio m o lon maṣe binu si

CAPRICON Dec 22 Jan 21 Jẹ onjẹ ti o fẹyẹ loni bi o bi ni awọn omo w ẹ n a a d rẹ t wa ki nka bir ku ki m ṣe ṣ lẹ

BERE FUN OJULOWO ADI-ELEGBO

"Congreve's Egbo Form—Ointment'

Atamatase ni egbogi "ADI-ELEGBO" yi i fun itoju egbo egbo orisirisi "EGBO—EṢẸ" n kakiri bi o ti wun ki jọ rẹ t le pẹ to, Adi egbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ti bi ẹr g gbogbo ti o ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo ti o bajin si u yio je i oju re ru wa soke, yio si pọn daradara fun bakaru ko si mo ae ewere ni yio si san pata pata. Alafia de si ọ niyen :

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si isale iwe yi ni egbe ranṣẹ lọ ra Bibẹko awon Eleru tabi onijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba e ra o.

Bere egbogi yi ni ṣobu awon :—

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.
WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street. Phone 22787

Ha! Kini eleyi O

OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile n kiakia o un re si da ra pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara pa ayan ati idun

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si d wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu un ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

AŞEJU

Lati Oju Ewe Keji

ọkunrin yi nba bọ bẹ titi ti ọba ilu fi n o wipe o ti tun di olowo aburo rẹ so lati mo ohun to tan mu ẹgbon o ı di olowo rẹpẹtẹ yi ALAŞEJU PẸRẸ NI TẸ Nigba toto asiko ti ọkunrin ma tẹ ni ojo kan.

Nigbati o jẹ ti o mu to yo tan o lọ ya batani ile to wa lati ma gbe bata ıi ile na jẹ ile pẹtẹsi o fi ile ile iṣẹ, ile igbẹ, ile idana ati ohun ti o tọ ki ẹni to ko le ni

Mo fẹ lati sọ fun nyin pe ati igbati awọn iyawo to ti salọ tun ri pe gbogbo nkan ntun ndara fun ọkunrin yi ni won ti tun pada wa sile

Nigbati owo bẹrẹsi gun ọkunrin yi olọra ilẹ nla kan lati kọ ile si ọgba awon ala gbaro won ro ile ıa won gba ilẹ na jọ won san igba ti odara lati kọ ile si tan

Loru mojumo ojo kan ni okunrin yi ro lo ka ı ararẹ pe nbari ki ile ti mo ya silẹ mo Batani yi di ile totọ si nı ilẹ ti mo ra ki ile ojo na tomọ ile to ya sinu Batani ti duro si ori ile ran gbadan sori ilẹ na gbogbo ilẹ kun je ji gbogbo ile kun lo pe si ara fun okoro ni orisiri gẹgebi o ti fẹ ati ẹda orisirisi ni eyi towu nigbati ilẹ mọ ti ara lleri ile ni o jẹ iya iẹnu fun wọn depo ti wọn ti nsọ wipe nigba wo ni ile dẹhin ao mọ ri ile nihin ni alẹ na kẹ ni boni eyiti wa eyi ba wọn lẹru dero ti awọn ti ile wọn sumọ ile na nko eru wọn salọ si adugbo miran.

Ki nma fa ọrọ yi gun ọkunrin yi fi iwe si o de wipe on fẹ si ile na on si fẹ ki ti ẹnu to mọ to wa nilu wa ba on si ile na ọkunrin yi fi iwe pe oba ati Ijoye ilu papa nigbati ile okunrin yi tun kun ola otun ro ni ok n rẹ pe nbori ki ati bata wa ni iwa ju le na ati ki risirisi a ıa k wa n ibẹ ati ke ki aga ti ob jẹ aga Gold liẹ ojo keji t mo gbo rẹ op pe si ib laila kukan in gbati ararilu tun ri eyi okiki tunkpa oe ao moi irur eyi ri o oro ti ile ri ati nso ati baba mo tuu ni yio

Ọro ara ilu na mu mi nia ran owa awon agbalagbo (Baba w) ba nipe ẹui ta şe onti ẹnikan koriri onni yio ri on ti ẹnikan koriri toto oşe bi owe ki a şe ka ti ọkunrin yi da fun awon ti o pe toto okunrin yi t. wẹ si ilẹ na bi oba ti de ẹnu ona yi aro ni ọkan ara rẹ pe nbari ki ibu sun ata a wa ni inu rẹ ati aso orisirisi baba de inu palo ato orisirisi on gan ta ba fẹ bẹbẹ lo so si gbogbo won igbati o tun de ile o sọ pe nbar ki ile onjẹ yi kun fun orisirisi onjẹ ati oti mimu bẹni orisirisi on to fi kari ile na nigbati a si ko to ti oba ati Ijoye ati awon gba jumo ti o fi iwe pe de tan ki won to bẹ si ni se faju ni okunrin yi fi kokoo le oba lowo oni oba ni on fe ki o si ile nigbati oba şi ile kun ẹnu ya oba ati awon Ijoye ti nwor tele lehin lati ri orisirisi on oso to wa ninu ile na lehin ti oba si ile kun ile na

---

ỌJA KO TA!

Nisiyi o, Ọja ko ta mọ, şugbọn ohun ti o yẹ ki ẹ se ti ọja yin yio fi ma ta bi akara gbigbona ni ki ẹ polowo rẹ sinu iwe IROHIN IMỌLẸ. Iwe Irohin kanşoşo ti o njade l'ede Yoruba lojojumo.

Iwo Ha Nfẹ Ile LEko Bi

Room	£3
Room	£4
Room	£5
Room / Parlour	£6
Room / Shop	£15
Flat (Lgos)	£20
Flat (EB)	£25

Ti o ba nfẹ ọkan ninu awọn ile wọnyi yaa tete lo si Ọgbẹni ODUSI— 187 Bamgboşe Street Lagos ni

de.de agogo mẹrin irolẹ si agogo mẹfa irọlẹ. ijafara lẹnu anfani nla kan ni eyi jẹ fun ọ pe o ri ile l'Eko

EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE FUN EGBOGI

"CYCLEVEN"

Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni patak fun Ọkunrin ti o si lagbara lati şe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri odẹ nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ şugbọn boya la le ri mẹwa ninu ogorun ti o le şe iwosan arun yi daradara. Awọn ẹlomiran lere wipe boya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati omusu ku ni. pa bẹ awon o bo lowo rẹ palapata

Şugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun die iyonu rẹ yio si tun ma bẹrẹ bakanna, Orisirişi Jẹdijẹdi ni o wa ckini ti o bẹrẹ nipa aiko ma şe igbonse dede tabi lojojumo, elomiran nipa ijoko ul ojukanna selu lojojumọ tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewo nipa ijẹ Şuga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jedijedi orişirişi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu lusu tabi ti o ba nmu wa lẹhin igbonsẹ tabi ba o nyo ti o ba şe lgbonsẹ tan ni, tabi ti nrin o ninu musu ui eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani fere wa idi rẹ ko ki o si danwo o işi mẹta nio daju wipe iwo yio bo lowo Je i patapata alafia yio de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogi sa igboro ilu Nsiria Bere re ni:—

Waterloo Medecine Store
Palm Church Streer Lagos
Phone282878 Nigeria, (Ọja Ita Faji
LAGOS

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYNAMREN** TỌNIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Tọ irki amọnu tilun ti gbogbo aga ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akr bara ati Ajẹbidan işẹ ara Agbalagba Ọkunrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, n gbakugba fun wahala tabi işẹ şişe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lọsan tabi awọn şaa ara rẹ gbogbo ki şefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iş: tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ojọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi jube lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di otun patapata inu rẹ a jọlọ ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi yabo dada kAra rẹ yio gbe kankan ni gugba yio sao pẹlu ioq adeubrode o iyẹn daj bi

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone.- 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

IROHIN IMOLE

IMOLE ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No 1,580 WEDNESDAY DECEMBER 8, 1965 (2D)

Awọn Alakoso Ijọba Fẹ Ṣe Ipade

EKO:- Ninu irohin kan ti a ri gbọ labẹlẹ fi ye wa pe awọn Alakoso Ijọba ilẹ Naijiria eyiti Alakoso apapọ Ijọba Naijiria ati awọn Alakoso Ipinlẹ mẹrẹrin ilẹ Naijiria yio jijọ ṣe eto ipade kan ninu ọsẹ yi ati pe o ti kọja asiko eyiti o ti pẹ ki awọn Alakoso Ijọba ilẹ Naijiria ti ṣe ipade eyiti nwọn ma nṣe papọ pelu Alakoso apapọ Ijọba Naijiria.

Irohin na tun fi ye wa pe a ko ti mọ ohunti awọn alakoso Ipinlẹ mẹrẹrin ati alakoso apapọ Ijọba yio ṣe ipade le lori nibi ipade eyiti nwọn yio ṣe na ninu ọsẹ ti a wa yi.

Ṣugbọn ohunti a lero pe awọn alakoso na yio jiroro le lori ni rogbodiyan to nṣẹlẹ lori eto abayọri ibo si ile Igbimọ aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti awọn enia Ipinlẹ na nja fun pe kọ tẹ wọn lọrun bayi.

Oniwe irohin kan ran wa leti pe laipẹ yi ni alakoso Ijọba Ipinlẹ agbedemeji Iwọ Orun Naijiria Oloye Dennis Osadebay sọ pe on pelu alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria Dọkita Michael Okpara ki yio ba Oloye Samuel Ladoke Akintọla olori ẹgbẹ Dẹmọ joko pọ gẹgẹbi alakoso Ijọba ninu ipade to ba pa wọn pọ lati ṣe ati pe awọn ko si gba pe on ni alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

MINISTA KAN NFẸ KI DẸMỌ ATI ỌLỌPẸ PAPỌ

IBADAN:- Ninu ọrọ kan to jade lati ẹnu igbakeji Minista Alamojuto eto alafia ilu fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgbẹni Ganiyu Abolude ni o ti ṣe alaye pe ki ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ati ẹgbẹ Afẹnifẹre papo eyiti o ṣe alaye bi awọn ẹgbẹ mejeji na ba le papọ ni eto ilọsiwaju ifọkanbalẹ ati iṣọkan le wa larin awọn ọmọ ilẹ Yoruba.

Ọgbẹni Ganiyu Abolude nsọ eyi ni ilu Ibadan ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ karun oṣu yi eyiti o ṣe alaye pe ohun ti o le mu ẹmi iṣọkan ati ilọsiwaju si ilẹ Yoruba ni pe ki ẹgbẹ mejeji na papọ lati le ma ṣe eto akoso bi alafia ati ilọsiwaju yio ti ṣe wa larin awọn ọmọ ilẹ Yoruba.

Ọgbẹni Abolude tun ṣe alaye pe ohunti o tọ bayi ni ọna bi ẹgbẹ Dẹmọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre yio tiṣe le papọ lati le ṣe ọna bi awọn ena ti ko si ni Ipinlẹ na ati awọn to nwa ipo ati ọna bi nwọn yio ti ma ṣe akoso ile ti ki iṣe ti wọn ma le ri aye da ọwo le ilẹ Yoruba.

IGBAGBO

Ọgbẹni Ganiyu Abolude tun mu ẹnu ba ọrọ ti alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Dọkita Michael Okpara sọ laipẹ yi pe ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun pe ki iṣe lati ẹhin odi Ipinlẹ Iwọ Orun ni ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na ti nwa bikoṣe lati Ipinlẹ Iwọ Orun ni ati wipe ohunti o nṣẹlẹ na yio si ma ṣẹlẹ si tabi pe ko ti lopin rara.

Igbakeji Minista Alamojuto eto alafia ilu fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun na tun ṣe alaye pe eleyi ti mu on ni igbagbọ pe ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria na si jẹ ohunti o jẹ wipe lati ọwọ awọn ẹgbẹ UPGA tabi pe ẹgbẹ na lo jẹ ipinnu nwọn fun awọn enia lowo lati ma da rogbodiyan to nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na silẹ.

Ọgbẹni Ganiyu Abolude tun kesi gbogbo awọn ọmọ ilẹ Yoruba to wa ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre lati fi ẹgbẹ UPGA silẹ ki nwọn si ṣe ọna bi nwọn yio ṣe le wa eto iṣọkan ati ilọsiwaju fun Ipinlẹ wọn ati pe ru isowọpọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Dẹmọ lo le mu ki ogo ati ifọkanbalẹ to ti wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria le pada bọ si Ipinlẹ na.

Oniwe irohin wa kan to ma nṣe akiyesi nkan ti ye wa ninu ọrọ rẹ pe laipẹ yi ni Ọgbẹni Gilbert Akinyele ti iṣe ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ tẹlẹ ti o si pada inu ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ọsẹ to kọja yi si ṣe alaye ki to to pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Awolọwọ silẹ lọgba ẹwọn ki nwọn si n ṣe Olori ilẹ Naijiria ki ohunti o ba pada de lati ọgba ẹwọn

---

WANTED

Advance Apprentice and Apprentice Printers.

Apply In Person
Irohin Imọlẹ's Office
16, Bamgbose Street,
LAGOS.

Ipade Ile Igbimọ Asofin Ijọba

Lati Oju Ewe Kini

ranṣẹ si Oloye Akintọla wipe, kio wa yan awọn Minista nitoripe on ti ri iwe gba lati ọdọ Ọgbẹni Esua wipe ẹgbẹ Dẹmọ lo wọle ibo na, Oloye Akintọla si yan Ijọba.

Awọn Ọlọpa ba Alhaji Adenro ati awọn ọmọ ẹhin rẹ ṣe ọjọ diẹ ki nwọn to da wọn silẹ wipe ki nwọn maa lọ. ṣugbọn lẹhin ọsẹ diẹ sẹhin ni Ọgbẹni Eyo Esua eniti iṣe Alaga Igbimọ eto ibo fun Ipinlẹ Iwọ Orun sọ wipe on ko fun Ọlọla Fadahunsi ti abayọri eto ibo ti nwọn ni kọja na nitoripe, eru ati manafiki wa ninu ọna ti nwọn gba di ibo na.

Ọgbẹni Esua tun ṣe alaye wipe, awọn akọwe eto ibo miran ko gba iwe lọwọ awọn Aṣoju bẹẹni awọn Ọlọpa si ri iwe ibo lọwọ awọn ẹlomiran ki o to di asiko ibo ati ni ọjọ ti nwọn dibo pẹlu, bẹẹni nwọn ko tilẹ dibo ni agbegbe miran ni Ipinlẹ na.

Lati igbana ni awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti bẹrẹsi sọ oko ọro ranṣẹ si Ọgbẹni Esua pe ohunti o ṣe ko dara.

Ọgbẹni Esua ṣe alaye ni nu iwe ti o kọ nigbana pe, ohunti o wu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti Ijoba wa lowo won nwon ṣe ni asiko ibo bi o tilẹ jẹ pe awọn nkan ti nwọn ṣe nigbana lodi si ofin.

Lati igbati nwon ti dibo na tan ni awọn Ọlọpa ti lọ si Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn si nso awọn enia ti nwọn nja.

Oniwe Irohin wa Ejo ngbaro yio lọ si Ibadan ni ọjọ ti nwọn yio ba ṣe ipade gbogbo awọn nkan ti nwọn ba si ṣe ninu Ile Igbimo na ni ọ ma gbọ ninu iwe Irohin wa ati awọn aworan awọn ọmọ Ile Igbimọ na ti nwọn ba lo.

Lati Oju Ewe Kini

Nigbati awọn Ọlọpa yio fi de awọn moto ti nwọn tẹ kọja lọ si Eko ko le ri ọna gba kọja lọ gbogbo awọn ero ti nwọn nlọ ati awọn ti nwọn nbọ ni nwọn nṣe idaro iku ọmọbinrin na ti nwọn nwo nilẹ ti o ti ku.

Awọn Ọlọpa ti gbe oku ọmọbinrin na lọ si Ile Iwosan lakulaku fun ayẹwo awọn Dọkita.

OLUWA RERE, GBA WA LỌWỌ IKU OJIJI O.

Printed & Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45 Campbell Street Lagos. 8/12/65